## Akiyesi

A nfe asoju mmakan ilu won ... Iseyin, Ibo, Ondo, Ilesha, Ibadan, Ogbomosho, Saki, Kaduna, Ijede, Oyo, Ile-Ife Zaria, Ibogan, KABBA, Otta, Ilaro, Aba, IKIRE: Kowe si Olotu 16, Bamgbose Stree.. Phone 21985

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

Oja kota! E ma Polowo Oja yin sinu Iwe Irohin Imole

VOL. IV No. 197 MONDAY MARCH 6 — MARCH 12 1961 KOBO KAN (1d)

# Awon Faranse tun fe yin etu Oloro won, Tafa. so pe a o fi oju won ri emmo bi nwon ba dan wo

ALHAJI ABUBAKAR TAFAWA BALEWA SO NILU EKO NI IJO ETI TI O KOJA YI WIPE GBOGBO ARA ILE FARANSE TI O WA NI ILE NAIJIRIA NI Y I O RI EMO BI IJOBA ILE FARANSE BA TUN LE YIN ETU OLORO (ATOMIC BOMB) WON NI OKUN YANRI SAHARA LORI EKERIN.

Ni ojo Ru ti ise ojo kini osu yi ni a gbo lati enu okan ninu awon ti ise alakoso ile ise Ijoba Faranse wipe Ijoba won ti pinnu lati tun yin etu Oloro won ni Okun yanrin Sahara ni u osu ti onbo yi ati wipe kosi enitı o le da won lowo ko lati ma mu ipinnu won se.

Bi eyin onkawe wa ko ba gbagbe laipe yi ni Ijoba Naijiria le asoju Ijoba Faranse jade kuro ni ile Naijiria nigbati won yin etu oloro won lori eketa, ati wipe osan kan oru kan ni Okun rin Asoju yi fi sare pale.mo ti o si sa lo.

Lehin eyi Alhaji Tafawa Balewa tun soro lori rogbodiyan Ile Kongo o so wipe, on mo wipe awon keta enia dudu ni won tubo mu oran Kongo di bi o ti da, loni yi ati wipe awon orile ede miran nse otelemuyen ninu oro Kongo, won nko Ipinle kan si ekeji, ni kukuru Alhaji Tafawa Balewa so wipe ohun ti o b u r u julo lati da ija sile larin omo Iya meji.

Ni ipari oro re lori Kongo, Olotu wa so wipe ni otito ni on n g b o igbe awon enia wa wipe ki a lo ko awon omo ogun wa ati Olopa wa bo, lati Kongo oni sugbon ki a ma se gbagbe wipe awon omo Ogun wa ati Olopa nja ijakadi lati mu ilu Kongo pada di orile ede alafia ati eyi ti ki yio si ogun tabi ote mo. Bi a ba ko won kuro nko, kini iyen se, Bi ogun ba de si Kongo k. yio sai kan wa, gegebi alawo dudu oni e je ka fi awon omo ogun wa sile.



Olola Abubakar Tafawa Balewa

## Olori Olopa Ogbeni Edet ati Kasafubu



Awon enia meji ti a nwo ninu aworan oke yi, ti nwon joko papo ni lati owo osi, Ogbeni J o s e p h Kasafubu, on ni a gbo wipe, o se alatako si Ologbe Lumumba. Eniti o joko ni owo otun ni Oga agba olori Olopa ti o nje Ogbeni L. O. Edet, on ni gbogbo awon Olopa ti o lo se onilaja nile Kongo tele lehin.

# IMOLE

ẸSIN ỌRỌ WA:
IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA
*Editorial Works & Office*
16, Bamgbos Strt, Lagos
Telephone:- 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street,
London W. 1


## Itiju ni awon Adete wonyi je fun Ilu Eko

Ohun a b u k u ati itiju nlanla ni o jẹ fun ilẹ Naijiria ati pataki fun Ilu Eko lati ri bi Adẹtẹ ti pọto ni ilẹ yi, ni gbogbo ibuṣọ ti moto Akero, (B u s - Stop) nduro si ni, enia yio ti ma ri awọn adẹtẹ wọnyi ti esinsin yio ma kun wọn gbayi.

Eyiti o wa buru ni bẹ ni wipe bi enia ba ti de ibuṣọ moto yi lati wọ moto, nṣe ni awọn adẹtẹ yi yio dede dide ti wọn yio si na kukunrekun ọwọ wọn ti o ti gẹ y ẹ n si Oluwarẹ, bi onitọhun ko ba si sora wọn yio fẹrẹ fi gun lẹnu.

Ọpọlọpọ ninu awọn adẹtẹ wọnyi ni egbo wa ninu ageku ọwọ wọn yen ti o si jẹ wipe, bi esinsin kan ba lọ jẹ egbo adẹtẹ yi, ti o tun wa ba le enia, Oluwarẹ yio fẹrẹ dẹtẹ pẹlu.

Eyiti o tun wa jẹ laburu baba ọbọ ni w i p e, awọn agbowo moto (Conductor) bi wọn ba de i b u ṣ ọ ti awọn a d ẹ t ẹ yiwa, wọn yio yara lọ ṣẹ owo (Change) lọwọ wọn, nigbamiran omi egbo ẹtẹ ti o wa lara awọn adẹtẹ yi yio ti yi gbogbo ọ w ọ wọn yi ti o jẹ wipe bi e n i a ba gba iru owo bẹ, ti Onitọhun ko si fọ ọwọ rẹ daradara ki o to jẹun dajudaju Oluwarẹ yio ko arun ẹtẹ.

Arun ti ko ṣe wo ki Olorun ma fi ṣe gbogbo wa ki nṣe w i p e a fi n y ọ awọn adẹtẹ yi ṣugbọn oni ohun ti o bo ju mu, o si ni ohun ti o dara fun ara. Nipa idi eyi, a ke si alakoso ile iṣẹ itọju ilu Eko ati alakoso ile iṣẹ iwosan, wipe ki wọn ro ikan ṣe ki wọn wa wọrọkọ fi se ada nipa, ọrọ awọn adẹtẹ wọnyi.

Nigbati I j ọ b a kọ ọgba were si Y a b a, pakirakita were nbọ dun n i l u Eko nitori idi eyi ki awọn Ijọba j ọ w ọ gba wa ki wọn ma jẹ ki gbogbo Ilu di adẹtẹ tan.

Yio je idanmu f u n gbogbo enia bi Ijoba ba le jọwọ kọ ile fun awọn adẹtẹ wọnyi, tabi ki wọn ba wa wa ibi kan ko wọn si.

Ohun i d ọ t i ati itiju ni wọn jẹ fun onile ati alejo wa.

## Okunrin kan ta Omo bibi inu re meji ni Poun mefa

Ọtta:-- Obinrin abiyamọ kan ti orukọ re njẹ Sikiratu Apata, ti o ngbe Ijoko Ọtta ni o lọ sọ fun awọn Ọlọpa ni agọ w ọ n wipe ọkọ on ti mu m e j i ninu ọmọ mẹfa ti on bi fun, lọ fun awọn Olowo ele wipe on fi wọn di P ọ u n mefa ti on jẹ ni gbeṣe.

Obinrin yi p ẹ l u omije loju ni o k u n l ẹ ti o nbẹ Ọlọpa wipe ki w ọ n jọwọ gba on, nitori wipe on ti wipe larin wakati kan ọkọ on ati awọn Olowo ele yi yio ta ọ m ọ on fun awọn Onişegun.

Were-were Ọlọpa ti obinrin yi ro ẹjọ fun gbera sọ odi abule Ijoko nibiti awọn omode wọnyi Jimoh Apata (ọmọ ọdun mejila) ati Karimu A p a t a (ọmọ ọdun mẹsan) gbe wa, Ọlọpa yi si gba wọn silẹ lọwọ Olowo ele, ati b a b a wọn ti wọn fẹ tan wọn fun baba Onişegun adahunṣe.

Ngbati ọwọ awọn Ọlọpa ba Baba Olowo ele; O sọ fun awọn Ọlọpa wipe ere pọun m e f a on ni awọn ọmọ wọnyẹn a t i wipe on fẹ mu wọn gẹgẹ bi Lebiranini oko on ni, ki ṣe wipe awọn fẹ ta wọn fun Baba Ologun Oṣo.

Aṣẹhinde aṣẹhinbọ ọwọ bole, folefole tẹgirimolẹ ọwọ ba baba ti o ta ọ m ọ rẹ, ni awọn Ọlọpa ba gbe janto, on ati B a b a Olowo ele, a t i alagbakọ (Akọwe Letter writer) ti o ṣe i w e li ọwọ si fun (Agreement) titi awọn ọ m ọ ẹ jẹ Ọrun wọnyi, Ọ l ọ p a si ti ko wọn ti mole.

Raji A p a t a ni orukọ ẹniti o ta ọmọ re yi nje, abule Ijoko Ọtta leti Ilu Ọtta ni o n g b e nṣe, iṣẹ agbẹ roko kura ni Ọkunrin yi nṣe.

## Oloye Rotimi Williams ke si gbogbo awon Odo pe won ni lati ma se ododo

LATI sọ ilẹ Naijiria di orilẹ ede nla ti o ni agbara Awọn Ọdọ inu re ni lati ni okun ati siṣẹ taratara ati lati ma se ododo ni gbogbo ọna lati maṣọ tọtitọ, ati lati tun ilẹ Naijiria kọ lati di Orilẹ ede nla, fun anfani gbogbo enia.



Iwọnyi ni Oloye Rotimi Williams Agbẹjọro Ọbabinrin Gẹẹsi fi ṣe ẹsin ọrọ rẹ nigbati o nba awọn ọmọ akẹkọ ile ẹkọ Kings College leko sọrọ Oloye Williams sọ pẹlu lati di ohun elo pataki fun ilẹ N a i j i r i a awọn Ọdọ nilati mura ki wọn ma sọ si ọrọ ilu ki wọn si ma gbe awọn Oṣelu lese ninu ọrọ ti yio mu anfani wa fun Orilẹ ede wa.

Ninu ibere, kan ti awọn Akẹkọ bere lọwọ Oloye F. R. Williams nigbati o pari ọrọ o fe si bayi wipe itọwọ bọwe ajumọse Ologun ti ilẹ Naijiria ṣe pẹlu Gẹẹsi kọ dara rara, oni odabi ẹnipe ati gbe iyi ati ogo Naijiria fun awọn Oyinbo.

Nipa ti awọn Ṣọja wa ti wọn wa ni ilu Kongo Oloye Rotimi sọ wipe o yẹ ki ipade Igbimọ Aṣofin ilọ Naijiria joko lori ọrọ na ki wọn bale ro o kan lẹ nitoripe ọrọ na le da ogun silẹ larin Naijiria ati Orilẹ-ede miran.

## White Brotherhood Lodge ki se Egbe Okunkun, Egbe iranlowo, Ife, ati Irepo ni

Ọkan pataki ninu ofin mimọ mewa ti Ọlọrun ti o wa ninu Bibeli mimọ sọ wipe "Fẹ ẹnikeji re gẹgẹbi ara re" ẹnikẹni tabi ẹgbẹ kẹgbẹ ti o ba si tẹle eleyi ko lodi si ofin Ọ l ọ r u n ṣugbọn ẹgbẹ melo tabi enia mẹlo lo mọ itumọ ofin yi ti o si npa mọ.

Nigbati Jesu nsọrọ ikẹhin fun awọn ọmọ ẹhin rẹ ni ijọsi ki wọn to k a n mọ igi o wi ninu ọrọ rẹ pe, ki ẹ fẹran ara yin gẹgẹbi emi ti fẹran yin ofin yi ko tete ye awọn ọmọ ẹhin rẹ n i g b a t i wọn nyọ lẹnu o wipe gbogbo yin ni e o ma dẹṣẹ nitori mi ni oru yi nitori ati kọ we rẹ wipe a o lu Oluṣọ agutan agbo na yio situ kakiri lati igbayi ni ofin iran ara ẹni lọwọ papa ti tuka pẹlu ara awọn ọmọ-ẹhin Jesu.

Dajudaju bi aba si ri ẹgbẹ ti o ntẹle ofin yi ko yẹ ki a jina ẹgbẹ na rara. ẸGBẸ UNITED BRETHEREN PRAYER GROUP ti adape re nje White Brotherhood Lodge jẹ ẹgbẹ kan ti o ka ofin yi si ti wọn si npa mọ. Ẹgbẹ yi ko yatọ si awọn ọmọ ẹhin Jesu ijelo, ti enia ko ba sun mọ wọn ko le mọ ohun ti ẹgbẹ yi nṣe.

WO IYOKU NI OJU EWE KARUN

# Ife lagba ohun gbogbo, Suru ni Olorun fi nseto ile aiye

Lati Ọwọ:— Ọmọ Aridẹgbaju Oke Ọla Oro

MOKI gbogbo enia ilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti lọkunrin ati lobinrin, ọmọde ati agbalagba, Oluwa ko ni jẹ kari ogun adaja lailai. Mo wa ki ẹnyin Musulumi ẹlẹgbẹ mi jake-jado ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti e ku ọdun oṣu Ramadani ti a wa ninu rẹ yi, Ẹsan towa ninu oṣu na ki Ọlọrun fi san wa, ki o si jẹki ari ọhin oṣu na. Ki Ọlọrun Ọba ajanu ki o fi ọna mọ wa, am amin. ati aṣẹ.

Mo beyin pupọ ẹ teti silẹ gbọ alaye mi dada nitori ohun ti o ba ba oju ba imu pẹlu, o si yẹ ki a fi otitọ ọrọ ye ara wa bada. Nitotọ otitọ ọrọ koro pupọ, o ṣoro gbọ seti, ṣugbọn o jẹ ju ogun lọ.

Ni ọjọ kẹtala osu [illegible] ọdun yi ni wọn tẹ irohin kan jade jade ninu iwe irohin Imọlẹ. Irohin na lọkan gbogbo wa patapata, gbogbo wa lo si ni ẹtọ lati sọsi ọrọ na dada bẹ na a si tun rika bakanna ni ọjọ ogan oṣu keji ọdun yi pe o ki a OMINIRA ara wa lotọ fun ilẹ IGBAMINA, ỌFFA, ati EKITI (Divission) lotitọ ọrọ na segbọ awọn Ẹgbẹ na ni Ẹgbẹ Olomi ati parapọ.

Akọkọ ibo didi sile Igbimọ Ijọba ipinlẹ Ariwa o ku si dẹdẹ. Mo bẹ awọn asiwaju Ẹgbẹ oṣelu wa na pupọ ki wọn maṣe fi ọrọ ti Divission yi ṣe ipolowo ibo rara

Ni otitọ ati ni ododo ipolowo ibo ni moka ọran na kun mọ si fẹ ki awọn agbalagba wa sorikodo ki wọn ro ọrọ na wa dada. Ọlọrun ọba alanu maṣe jẹ ki ohun ti o wun pawa (Ami) Nigbati o jẹ ṛe ako pada lọ si ipinlẹ Iwọ-Orun mọ ti o jẹ wipe a fe da duro ni o yẹ ki awọn agbalagba rori dada papa awọn ti o jẹ ọmọwe ki a rori dada nitori bi oni tiri ọla le ma ribẹ, ni baba alawo fi difa Ọrọrun nitori Ibo ti a di kọja nijọsi anlọ si Iwọ Orun a ko lọ si Iwọ Orun ni a fi ṣe ara wa leṣe. Awọn Ijọba Ipinlẹ Ariwa ti ṣe tan nigbana l a t i fun wa ni Divission ti ẹfẹ ma fa lẹse yi, ṣugbọn igbati awọn ẹgbẹ kan gbe ọran Ipinlẹ Iwọ Orun lelẹ ni wọn fi (Cancelled) parẹ pata pata.

Ti ẹba wa ripe anlọ si Iwọ Orun ko bọ si mọ, ki ẹ sọ si eti araiye gbọ pe eyi ti ẹ sọ nipa pe anlọ si I w ọ Orun, iyẹn ko bọsi mọ, ati pe ẹti mọ pe ko le bọsi, irọ ni ẹnpa f u n wa, bẹni ka tan ni ka mọ ọgbọn pin nibẹ.

Ti ẹba sọfun wa bẹ tan, a o wa mọ pe ẹfa nkan ti ko bọsi, ki a tun fa omiran wo. Lotitọ ko si ẹniti yio gbọ ọrọ Divission ti inu rẹ ko ni dun dada, ṣugbọn Ifẹ lagba ẹjẹ kia fẹran ara wa na ki a to gba Divission yẹn Nitori ti a ba g b a Divission, ibikan ni a o fi ṣe ibudo Ijọba wa, igba ti a ko n i f ẹ larin ara wa, ti awọn kan ni ki a gba Divission ika ni yẹn, Ẹ ma ṣe jẹki aro ti ara wa nikan, ẹ jẹ ki a ranti awọn tombọ lẹhin ti a ba ti gba Divission.

Ibudo Ijọba wa to ro dada, ti awọn agba yio si rori d a d a pẹlu ifẹ ti ifẹ ba si ti wa ibikibi ti a ba gbesi na ni yio tẹ wa lọrun d a d a. Wọn tun nsọpe Ilọrin nio wa nibi omi ojo, ti iyẹn ba jẹ bẹ nijọhun ni yẹn ki ṣe asiko yi rara, ki a sọ otitọ ọ r ọ, nijọhun Ilọrin lema tuwa jẹ, ṣugbọn ki ṣe Ilọrin nikan, awọn ilu miran tun wa ti wọn manṣe bẹ na: awọn bi Ọyọ, Ibadan, pẹlu awọn I l u miran na ma nṣe bẹ laye jọhun, ṣugbọn gbogbo iyẹn ti do pin nisisiaiyi.

A wa gan ni a ma nko ọrọ wa lọ si Ilọrin, jẹjẹ ni Ilọrin duro, Ilọrin ko ranṣẹ pe ẹnikan r a r a, ṣugbọn nigbati ko si ifẹ larin ara wa, anko ara wa lọ si Ilọrin lasan, ẹwa ni awọn Ilọrin njẹhun ilẹ wa?

Mo wa fẹ ki ẹ gba pe Ọlọrun ki nṣe to aiye, asiko jọhun ni asiko jọhun pẹlu wahala, asiko isisiyi tun dara, ṣugbọn ki ẹ gba wipe akoko k a n tumbọ ti yio dara juyi lọ.

# Oja kota, E ma polowo Oja yin sinu Iwe Irohin Imole

# Olori Omuwe Omo Geesi



Omidan Ann Long, ọkan ninu awọn Omuwẹ ọmọbinrin ọmọ Gẹẹsi ti o lọ si ere Ije ti Olympic ti wọn ṣe ti wọn ṣe ni Ilu Rome ni ọdun tokọja 1960.

Omidan Long ndan ara wo, fun aṣọ ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ wọ fun Ere Ije Olympic. O m i d a n Long jẹ Olori awọn Omuwẹ ni ilu Gẹẹsi ọdun kẹwa ie ti o si ti jẹ Olori awọn ti o mbẹ w, inu omi.

Ninu Ere Ije Olympic na awọn ọmọ Naijirin ko gba ẹbun kankan, ṣugbọn wọn sa ipa wọn, O l o y e Akin Dẹkọ ni o ṣe iko awọn ọmọ Naijirin. Oloye Awolọwọ ati Dọkita Nnamdi Azikiwe si lọ wo iran ere ije na nigbati Oloye Awolọwọ de, o ṣe kilọkilọ pe a gbọdọ mura atipe Ijọba Apapọ gbọdọ ṣe itanlọwọ fun wọn.

# Nipa Oro Kristi

Lati Owo.-- PAUL AGBOOLA OLADIPO
31, Idumagbo Avenue Lagos Nigeria.

## Idahun si oro Dele Atolagbe

OLOTU! Jowo gba mi laye lati da Ogbeni Dele Atolagbe lohun, Owe: 26:5 Da Asiwere lohun gegebi were re, ki o ma ba gbon ni oju ara re.

Dele Atolagbe ko si iou Irohin Imole ti ojo 6/2/61 ni oju ewe karun pe on ko mo ere ti Ogbeni Agboola ri gba n i n u ibere to ma se, ati pe Ogbeni yi ko ju omo odun mejidilogun lo. E si mi fun Ogbeni Dele yi ni pe Jesu ti pari oro won ninu Matteu 22:29 Jesu dahun o si wi fun won pe, Enyin sina, nitori enyin ko mo iwe mimo, e ko si mo agbara Olorun.

Ni igba ti Jesu wa laye won bere oro lowo re o si da won lohun emi ko wa rii ti Ogbeni ala yi ko kan yi yio tun ma wadi oro lowo mi si Jesu na bere lowo awon enia won si da lohun: Ibere na ati idahun na wa ni Matteu 22:41-29. Ibi ti Bibeli si ti fun wa laye lati ma gba ibere 2 Timothy 2 : 23 sugbon ibere were ati a l a i n i eko ninu mi ki o ko, bi oti mo pe won ama da ija sile Bibeli ati K u r a n i gba wa laye lati se ibere Surat 16: 43, tun gbawa laye lati se ibere nitorina iwe mejeji ti fun wa laye lati wadi oro lowo awon enia Olorun, sugbon Ogbeni Atolagbo yi je alayi mokan enia ati Afoju si oro Olorun bi ko ba je be ki ba ti wadi lowo enia Olorun kan pe eri wo ni o fi awon enia yi lokan bale lati ma se iru eyi ti won se yi.

Mo wa fi oro Ogbeni Atolagbe, we oro omo Atiro, to ra bata lo si ile fun baba re, oro lo fe gbo. Awon enia si so fun mi pe Ogbeni yi, ka iwe sugbon ko ka lakaye mo. Mo gbani iyanju ki otun lo ko lakaye kun iwe re nitori mejeji lo jiso po, nipa ere wo ni a ri gba ninu ibere, e wo lokan o nipa ere temi. Eni ti ko dani ni oko owo ka le pe ni arungun. Ni igba ti awon to patan iye odun mi fun e ti won ko fi kun pe, nise ni won yawo san owo ile iwe mi, ki lo wa kan o ni ibe nitorina ko lo panu re de lati ma bere iru oro baranda be lowo mi sugbon emi ko fi binu rara, nitoripe mo mo pe o ye ko ye o to ni ati pe ogbon re ku die. Nipa ti omo odun mejidilogun eni to so fun e iwo pelu re ikan ni eje, iwo ko mo pe ni igbati Jesu di omo odun mejila ni oti bere si ko awon to ju baba re lo ni oye ori ni oro Olorun bi aba wo Luku 2: 46-47 ni ese iwe yi won tun bere lowo re wipe o si da won lohun.

B i b e l i si so fun wa pe ranti eleda re nisisiyi ti ojo ewe re nigbati ojo ibi koyi ti de ati ti odun koni sunmo etile nigbati iwo yio wipe emi koni inu didun, ninu won Oniwasu: 12:1. Iru awon ese wura bayi lo mu mi lokan bale lati mase ise Oluwa lati igba ewe mi, iwo to dagba ati eni to patan iye odun mi fun e, e mura lati mase ti Oluwa gegebi ti emi na ki ile kun anu to pade.

Nitori igba kan nbo wa ti ako ni ri enia ti yio soro O l o r u n fun wa. Amosi 8:11: akiyesi i, ojo na de ti Oluwa wi, emi yio ran iyan wa si ile na ki se iyan ti onje tabi ongbe fun omi sugbon iyan gbigbo oro Olorun. Kurani Surat 25 Ayat 22.

Sugbon emi ki se omo odun mejidilogun rara ki otun lo bere lowo awon omtan re daradara. Nitori pe iwe Mimo so fun wa pe E ma wa di ohun gbogbo daju ki esi di eyi to dara mu sinsin 1 Tessalonika 5 : 21.

KOITI PARI

# IGbomina, Offa, Ekiti, e se Ara yin ni okan (apa keta)

Lati Owo-- M. A. ODEKUNLE

MO KI NYIN G b o g b o enyin ti e nka iwe Irohin Imole, papa enyin omo ile Igbomina, Offa, ati Ekiti ti e ti nka ohun ti mo ti ko nipa ti Division fun ile wa lati bi ose keta seyin, ki Olorun ninu anu Re ko tubo tu awon Ijoba ile ariwa ti a o gba Division na lowo nwon, ninu ki nwon le fun wa ni i r o w o, irose laisi ija gegebi Naijiria ti se gba O m i n i r a laisi ija tabi ita eje sile.

Mo ni lati be gbogbo enyin Egbe Olomi pata pata, mo tun be nyin ni oruko Olorun ati ni oruko eniti o je Alalo Igbomina, Offa, ati Ekiti ke jawo ninu apon ti ko yo, ke da omi ila kana. E lowo mo nbere lowo enyin Olomi, Kini ohun iwulo, tabi ohun anfani ti ati gba lowo Ilorin ti ki se pe iya na la tun nje labe nwon mo fe ke dahun ibere mi yi, nitori ko ye emi to, mo si wo lati oke de ile, emi ko ri ohun ti Ilorin ti se fun wa rara ti enyin Olomi le ku le lori, bi o ba si wa, to! ki e fun mi ni idahun.

Ekeji nipe o han si Olomi Igbomina, Offa, ati Ekiti pe ko si ohun anfani kan ti anri gba lowo nwon, ayafi bi nwon yio ba gba lowo wa, gbogbo nyin ni e mo eleyi daju, sugbon loju temi o dabi enipe ife owo ni mbe lokan egbe Olomi, ile Igbomina, Offa, ati Ekiti ni nwon se le gbe ile Igbomina ta, bi o base tori owo ni e se nse Egbe Olomi, kinise ti e o ma ja futafuta fun idagbasoke ile Igbomina, Offa, ati E k i t i enyin Egbe Olomi mo fe ke kiyesi ara nyin, fun apejuwe, kinise lati bi osu mejo sehin ti e ti dibo Local Council tan, enyin Egbe Olomi lo wole, kinise ti e o le ja ija na pe ki won tu Caretaker ka ni Ilorin, ki enyin to wole ma ba Council N. A. Ilorin lo.

WO IYOKU NI OJU EWE KARUN

# Omo Jaiye-Jaiye wo Aso Asiko



Omoge ti e nwo ninu aworan yi je okan ninu awon Omo Jaiye-Jaiye ti ilu Geesi larin awon aso titun ti ile Dior, ti o fanso awon Olola omo jaiye-jaiye ati awon Olowo ni omo jaiye-jaiye yi ti ra okan.

Awon orisirisi aso ba wonyi ni awon ti won wa ba se ajoye O m i n i r a Naijiria wo ni ojo kini osu kewa odun tokoja. Nitorina o ye ki ama wo aso ti ile wa na.

# Akiyesi Pataki

Emikeni ti o ba ngbe agbegbe ilu wonyi Mushin, Iju, Odi Olowo, Ikeja, Owode, Otta, Oshodi, Ifo, Atan, ati Onibuku, ti o ba si fe ra iwe "IROHIN IMOLE" ki o lo si odo Asoju Irohin Imole Ogbeni Ebenezer Folarin ti o ngbe No 36, Buari Street Olorunsogo Mushin.

EMA KA IWE "IROHIN IMOLE" NIGBA GBOGBO KI E SI MA POLOWO OJA YIN SINU IWE RE

# IWE SI OLOTU

## Anfe Ile Iwosan (Hospital) ni Ilu wa Omupo.

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba gba mi laye lati jẹ ki"nsọ fun gbogbo ọnkawe Irohin Imọlẹ nipa wahala ti anṣe ki a to de ile iwosan ti Ajaṣẹpo tabi ti Oro tabi Igbaja, papa Offa, bi enia kan ba fi ara ṣeṣe nilu Omupo a fi bi ẹtun nṣọ mọto ti yio gbe nyin de ilewosan ti Ajaṣẹpo, tabi ti Oro papa Ọmọ ile ẹkọ, bi nwọn ko de awọn ilu ti mo da oruko nwọn yẹn ko si ile-iwosan fun wa, bẹ ni awọn ilu ti mo daruko nwọn yẹn ko si eyiti o pọ tu ilu Omupo.

Olotu modupẹ o, Ọkọ Ọba ko ni ṣa yin lẹṣẹ o.

Emi ni:- LAWANI AKANBI

Ọmọ Omupo

---

## Animahun Baba Wuraola D' Ologbe

OFFA:- Jakejado gbogbo ilu Ọffa ni o mi titi nid ede Agogo meje owurọ ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kẹrindilogun oṣu ti o kọja yi nigbati agbọ iku Alagba oninure kan DANIEL ADEBỌWALE IṢỌLA.

Agbọ wipe Ọmọ ilu Abẹokuta ni alagba yi iṣe, ati wipe iṣe Gbẹnagbẹna ni iṣẹ arakunrin yi, o si ti wa fidi si Ọffa lati bi ọjọ mẹta kan.

Ọlọrun fun Alagba yi ni anfani ati lo ọdun pipẹ lori ilẹ aiye o si mu Isinku Alagba yi dun to bẹ ti o jẹ wipe ko ṣe fi ẹnu rohin Oniwasu Pastor J. A. Aderibigbe ni o ṣe wasu nibi isinku Ologbe yi.

Awọn enia pataki ọmo Ẹgba ti o pesẹ sibi isuku yi ni S. T Ṣhotunde, Osho the chair, Ṣhobọwale, ti onṣiṣẹ ni Enginering yard, J. O. Ọlaniyi, Amos Lagoke, ati gbogbo ọmọ Ẹgba ti wọn wa nilu Ọffa ati agbegbe rẹ.

Ade Isọla alemu lara Animahuu Baba Wuraọla ọmọ Ogundipẹ Arapasowu, ọmọ yema logun, ọmọ afogusorọ Animahun aramahun ọmọ ikoti mọbọ ṣe fukẹfukẹ Ọmọ Ẹgba ile Orun rere o, Majẹ Ọkuu, majẹ Ekolo ohun ti wọn banjẹ lajule ọrun ni ki o ma jẹ odi gbere o darinako otun doju ala kato rira Sun re o! Sun re o!! Sun re o!!!.

---

## Agunbiade komo jade, omiringindin

Ni ọjọ Alamisi 23rd oṣu Febuary 1961 ni Ọgbẹni yaya Afaya Agunbiade ṣe ikomọ jade ọmọ ti Ọlọrun fi ta lọrẹ lati ọdọ Iyawo rẹ Sidikatu, o fi ile pọn ọti, o si fi ọna roka.

Ni agogo marun aṣalẹ ọjọ na ni ẹse awọn gbajumọ gbajumọ ti pe sile baba Tunfulu yi, nibẹ ni nwọn t ṣe ariya ikomọjade na, o dun o si larinrin, eyi ni orukọ ti wọn fun ọmọ titun na, Adijatu Kubura

Gbogbo enia jẹ, nwọn mu, nigbati Isọnu ba wọn jẹnu re, Ọlọrun ko wo ọmọ na, ki akoko tirẹ jẹ ere fun Iya ati Baba, ki nwọn si le mọ igba tirẹ ni yana ọtọ.

---

## Owe Yoruba

Aṣe bajẹ ṣe bi ti on lari, aṣe buruku ẹku ara fuu.

O ri ẹsẹ were obu ṣe ogun, ni ọjọ wo loto ri ti ọlọgbọn. Ọlọgbọn ti on rin ni ori apata ti otun yẹ ibẹ wo.

OBERẸ NI OJU EWE KEJI

Lakọkọ Egbe yi duro fun iranlọwọ fun ọmọ ẹgbẹ ti o wa ni idubulẹ amodi ,enia kan ba ku ninu ẹgbẹ wọn awọn ẹgbẹ yi ti da owo kan pamọ sinu apo ifi owo pamọsi won, awọn yio mu iye ti o jọju ninu owo yi won o fi ta awọn Ebi Ologbe yi lọrẹ. Bi ọmọ ẹgbẹ kan ba si bimo bakanna ni.

Lẹhin eyi awọn ẹgbẹ yi wa fun iranlọwọ fun ọmọ ẹgbẹ eyiti ko ni ṣe nwọn a wa iṣẹ fun. Ẹgbẹ yi mọ nipa adura pupọ, wọn ni ife isin ti wọn, ẹgbẹ tiwọn ki ṣe ẹgbẹ okunkun, tabi ẹgbẹ ti nwa osho kiri bikoṣe ẹgbẹ ti Ọlọrun tikalararẹ da silẹ fuu irẹpọ larin awọn ẹda ọwọ rẹ.

Bi o ba jẹ wipe ododo ni awọn ohun ti a sọ wipe ẹgbẹ yi nse yi njẹ, o yẹ ki gbobgo wa sunmọ ẹgbẹ yi ki ajumọ gbe orukọ Ọlọrun ga.

---

## Igbomina, Offa, Ekiti, e se Ara yin ni okan (apa keta)

Lati Owo-- M. A. ỌDEKUNLE

O BẸRẸ LATI JU EWE KẸRIN

Ti o ba si jẹ Parapọ lo wọle, pẹlu tolasi ni, ni alubarika ofin, Parapọ yio ti bọ si ori aga.

Owe awọn Agbalagba wọn ni, A rin gbẹrẹ ni yiọ mu oye dele, asure tete ko ma ni ri oye jẹ o. Baba Alawo a ku, Oniṣegun a rọrun, Adahunṣe ko ni gbe aiye ra, o to akoko ki gbogbo wa rọnu ka le gba Division ilẹ wa, ki igbesi aiye gbogbo wa ati Ọmọde ati Agba Imale ati Onigbagbọ, Parapọ ati Olomi, ki aiye wa bale toro bi omi ti o fi arọ pọn.

Olotu mo dupẹ, iṣẹ nyin ko ni bajẹ.

---

## John Kenedy Olotu Ijoba Amerika titun



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Ọlọla John Kenedy ti iṣe ọkan ninu Omọ Ọkunrin Arakuyamu ni igboro ilu Amerika, ti o tun pada di Baba Ẹgbẹ ati Baba Isalẹ fun gbogbo ilẹ Amerika.

Gbogbo awọn ti o ti njẹ oye Baba ẹgbẹ sori aga alaṣẹ nilẹ Amerika, Ọgbẹni John Kenedy yi lo kọkọ jẹ ọlẹsin ti ijọ Aguda. A gbọ irohin wipe larin akoko ti yio fi wa lori aga gẹgẹbi Baba ẹgbẹ yi, yio ni anfani lati wa bẹ ilẹ Naijirio wo.

O BERE LATI OJU EWE KINI

Loti oro ile Ariwa orile ede Afrika Ilu Gusu nibiti awon enia Afrika ti o wa nibe je fuafun ti won si korira awa ti a je dudu, dero ti o je wipe pipa ni won nia apa wa awon orile ede yi (South Africa) wa fe wo igbimo gbogbo Olotu Ijoba gbogbo orile ede agbaiye. Alhaji Tafawa B a l e w a so wipe on yio tako orile ede yi bi awon ba de ibi ti opa gbe duule on o ri ba Olotu Ijoba won Dr Verwoerd fi ija pa eta, on yio si ta ko won wipe won ko gbodo gba awon S o u t h Afrika si Awujo won nitoripe akorira enia ati kenuna ni won, ohun ti o mu won pe ki won ma pa awa enia dudu yoku ni ipakupa bi eran ni oni yio fi se esin ojo on bi on yio ba tako won.

Alnaji Tafa Balewa ti ba oko ofurufu lo si ilu Oyinbo ni ojo abameta to koja yi lati lo sibi ipade yi.

## Kini Olawoyin gbe nigba awon Egbe Olomi ewe?

OFFA:- Olorun Oba so ninu iwe mimo wipe iwo omo enia, dide, iwo simba oruko omo iya re je, iwo sebi eni ko ri o m, tabi iwo sebi eni dabi iwo tikalare n, iwo ma mo banje ni so, nigbati iwo ba dekun lati ma banje nigba na, a o dide si o, a o si ba o je.



Ogbeni J. S. Olawoyin

Awon egbe Olomi kori ra Ogbeni J. S. Lawoyin tobege, nwon gbe ju sipo ewon, nwon gbagbe owo kan so bayi wipe, ile oba ti o jona ewa lo bunkun. Nwon duro dupe ewa, sile sibe nwon tun nlepa re ki ri, tobe ti o fi ni lati lo ko ba awon O l o p a wipe ki nwon gba on kuro lowo Egbe Olomi ti nwon nfi ojojumo lepa emi re kiri Haba!

A ni ki ole sa, o sa, a ni ko ju ohun owo re sile o ju u sile, kili e tun fe ki Ole na se?

## E wa fun Oju ni onje tire

**EGBE IREWOLEDE (OKEYA) Lagos Branch**

"Fi tayotayo pe Enikeni lati wa wo ere Omo Ibile ilu Oke. Oruko Elere na ni RAMONU ELEGUN JOROMO TO'MO ERE ALADUN ISE. Ere na yio bere ni agogo mejo titi di agogo merin oru ni ojo I s e g u n ti ise ogun osu keta o d u n yi (20/3/61) ni G l o v e r Memorial Hall Lagos.

Irohin koto afojuba eni to ba ri lo le so. Owo iwole bere lati sile Meta de sile marun 5/- Front seat: Back seat 3/- Ere na aju iye owo ti e fi wo ile lo.

A ki gbogbo awon Odo'mokunrin pelu Odomobinrin ati gbogbo awon Agbalagba Oluwa je ki ojo na ba wa Laiye pelu A l a f i a Ara. Gbogbo ibiti e o ti ma ra Tiketi niwonyi:- Salami Koshowolu, 60, Victoria Street Lagos. (2) Yesufu Adigun 176, Victoria Street Lagos. 3. Salawu Ayanda, 27, Idumagbo avenue Lagos. 4. Memudu Bello 67, L. E. D. B. Shop. Idumagbo av. Lagos. 5. Sule Akosile 12, Ajanaku Street, Lagos. 6. Jimoh Dokita 201, Sangross Market, Lagos 7. Alia Baba Ayinke, 11, Mogaji Court, Lagos. E mu ra sile o, Oluwa yio so wa tayo ojo na. Amin.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21585. Olotu: E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street Surulere, YABA.

FUN OWO IROHIN IMOLE ODUNKAN

EKO:- Siletmerin ati kobo merin (4/4d)

Ijumiran ni Naijiria ati Oke Okun:- Sile Mefa ati Kobo Mefa (6/-6d)

## Federation of Nigeria Second Development Loan.

The Central Bank of Nigeria have been authorised by the Federal Minister of Finance to raise in Nigeria a Federal Government loan of £10,000,000.

The Stocks to be issued will be :-

£2,000,000 5% FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1967. £4,000,000 5½% FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOP-MENT STOCK 1977. £4,000,000 6% FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT STOCK 1985

Interest which will be paid half-yearly on the 22nd September and 22nd March will accrue at the rates shown above and repayment will be made as follows :-

5% Federation of Nigeria Second Development Stock, 1967—on 22nd March 1967.

5½% Federation of Nigeria Second Development Stock, 1977—on 22nd March 1977.

6% Federation of Nigeria Second Development Stock, 1985—on 22nd March 1985.

Application lists for the loan will open on the February and close on the 22nd March both dates inclusive. Applications must be in multiples of £10 and can be made only on the special forms available at banks throughout the country. Application for different stocks must be made on the different application provided.

The stocks will be issued at par and payment in full must be made with applications (i. e., £10 must be paid for every £10 of stock applied for ). Receipts will be issued for payments and will later be exchanged for Stock Certificates. If desired, payment may be made by means of a draft on a United Kingdom bank but payment in this way may be made only to the Central Bank of Nigeria direct, accompanied by the relative application form.

Notification of allotment will be made direct to subscribers by the Central Bank of Nigeria as soon as possible after the 22nd March and stockholders will be advised at the same time when to collect their stock Certificates from the banks where they submitted their applications.

Pending the operation of a Stock Exchange in Lagos, prospective buyer and sellers of the stocks should after allotment has been made, approach their own bankers who will consult the Central Bank with a view to effecting a market.

Further information may be obtained from the Prospectus available at banks on and after 22nd February

R. K. C. GIDDINGS,
General Manager

*Central Bank of Nigeria,*
*Tinubu Square,*
*Lagos.*
*February, 1961.*

## UNITED BRETHREN PRAYER GROUP

**Egbe fe enikeji re gegebi ara re**

Eyiti opolopo enia mo si "THE WHITE BROTHER-HOOD LODGE" Nje iwo ha mo ohun ti agbara adura je bi? Tabi o ha ti gbo nipa ise iyanu ti Egbe oke yi nse fun eniti o ba wa ninu i d a m u, ti o wa ninu aiye bi enipe ko si l'aiye. Lorokan k o w e si Akowe gbo oke yi fun Iwe Alaye pipe nipa Egbe yi.

SECRETARY BOX 64 YABA NIGERIA.